WANTED

Two An Adv.nced Apprentice Printers.

**Apply in person to:-**

Modupe Printing Press
16, Bamgbose Street
LAGOS.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**READY FOR SALE**

Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI ỌMỌGE- IMARO
APA KẸTA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
**Price 2/-**
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
**Postag Extra**

VOL. I No. 46, WEDNESDAY MAY 14, — MAY 21, 1958 KỌBỌ KAN

# "OMO OLORIMEJI" Ku Iku Aburadi

JAPAN- Awon oyinbo ni suru jojo, bi nwon ba bimo abami, kaka ki won ropa nwon o se itoju re, nwon o si woo dagba lati ba wo yala rere lo wa se nile aiye, tabi ibi.

Obinrin kan tı o nje Aiṣa ti ọ k ọ rẹ ti ku bı awọn ọmọ abami kan, ọmọ na jẹ ib ji, o r i meji ni ibeji na ni, ṣugbọn ninu agbẹdu kanna ni awọn mejeji njẹun si, olukuluku si ni ẹsẹ meji-meji tire lọtọtọ ati ọwọ meji-meji, nwọn wa ni ikọjusi ara w ọ n. Bi ọkan ninu w ọ n ba jẹun, ekeji ko ni jẹ, awọn mejeji yio si yo bakanna.

Iya wọn a ma gbe wọn kakiri, a si ma fi wọn gba owo, lẹgbẹ-lẹgbẹ ni nwọn nrin gẹgẹbı akan. Nigbatı o ṣe, ọkan ninu awọn ori mejeji bẹrẹ si ṣe aisan, de ipo ti o fi nilati lọ jẹ ipe Ọlọrun.

Ẹru wiwuwo wa de si ọkan ti o ku, ko le r i n ọgọrun ẹsẹ ki o to bẹrẹsi lagun fẹrẹfẹrẹ, ẹru di ti on nikan. Nigbati o ṣe, o lọ si ile alaisan, o ni ki nwọn juri on, kı nwọn yọ ekeji on yi kuro lara on, nitoripe, o wuwoju, o si nda oorun pa on.

Awọn Dọkita sọ fun pe kole ṣese, ni iwọn ıgbati ekeji rẹ tı ku ni kı on na maira, eyi ko dunmọ ni inu, o fẹrẹ maiti kuro ni ibe, nigbati o ṣubu lule ti o si ku eyi ni o p i n ọmọ Olori meji.

## AWON IWE KOSEMANI TI OWA NILE FUN TITA NISISIYI

| | |
|---|---|
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalın Ajẹbidan | 2/6d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan pẹlu Itumọ Ala | 20/- |
| Itan Aladun lede Yoruba | 3/- |
| Ajiran Ilu Oku | 3/- |
| Waka Bisiriyu Apalara | 1/- |
| Itumọ Ala ati Itumọ Am: ;ra | 3/- |
| Iwe Owe Yoruba | 3/- |
| Psalm Iṣẹgun Ajẹ ati Aiye pẹlu Turari | 17/6d |
| Turari Itaja, Ẹyọnu Ajẹ ati Adura | 10/6d |

Fi owo ọja rẹ ati 1/- ranṣẹ si :-

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

AWỌN IWE TI A ṢẸṢẸ FẸ TẸ JADE

Igbo Eṣubeleke (kikun) 4/6d, Irin Ajo Ajanpako (kikun). 4/6d Ayunọrınbọ ati Panpalaṣọ 4/6d, Ajiran Ilu Oku (kikun) 4/6, Ṣebotimọ Ọrẹ mi 3/-, Mafarọ Ṣere 3/-, Igba ko lọ bi Orere 3/-

Akiyesi :- Ẹ o ma gbọ nigbati o ba jade

## Arabinrin 'NYLANDER' yio pari 'Eko Onje' kiko re



Arabinrin Hannah Nylander ti iṣe ara ılẹ Ghana yıo parı ẹkọ rẹ ninu ẹya onjẹ laipẹ ni Ile-Ekọ giga ti awọn Obinrin 'Western College f o r Women' ni Cincinnati. Arabinrin yi tan mọ Ọgbẹni Evelyn Amarteifio ara ilu Ghana ti o bẹ ilu Amẹrika wo laipẹ yi.

Ni ilu Amẹrika yi, a fun aya Ọgbẹni Evenlyn Amarteifio ni oye iwe ni 'Western College'. Arabinrin Nylander nkọ Ẹkọ nipa onjẹ ti o wulo fun ara, eyi ti o dara fun ọmọde ati agba. O si nkọ bi a ti ṣe nse o n j ẹ pelu, ati gbogbo nkan ti o si jẹ imọ eto ile. Arabinrin Nylander si ngbadun iṣẹ rẹ yi.

# IMOLE

ESIN ORO WA:- IMOLE DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*
**16, Bamgbose Street, Lagos**
**Telephone:- 21985**

*London Office:-*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE
PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE
177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMOLE" ODUN KAN

**EKO**— Şile Mẹrin ati Kọbọ Merin (4/4d)

Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Şile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)


# IJAFARA LEWU

Ohun pataki ti o fa ọrọ akọle wa ọsẹ yi ni wipe, nipa Ebute ọkọ nibi ti ọkọ Katilini ti o nduro ni Apapa gbe nduro si, ko dara rara, owe agba lo sọ bayi wipe Igi ganganran magun mi loju okere la ti nwo Ebute ọkọ na jẹ eyiti o lewu pupọju, paapa julọ fun asiko igbati awọn oşişẹ ba fẹ wọkọ sọda wa si Eko, ko si wipe ki awọn ti o wa ninu ọkọ na raye bọsile ki awọn ti yio wọ to ma bẹ sinu rẹ, igbamiran nwọn ma nfi aya ko ara wọn, o si ma ndi ija.

Nitori eyi a kesi awọn alamojuto ọkọ (Port Authority) pe ijafara lewu, ko ma ba si wipe ẹ wa dahun ibere ti ẹ ko mọ ọwọ rẹ. Paapa julọ irufẹ Ebute bẹ ko tun yẹ Apapa wa yi mọ, nitori ẹmi ko pe meji, a gba nigbakan ti awọn ti o nwọkọ ko pọ, şugbọn nisisiyi, a dupẹ a tun tu ọpẹ da wipe Oluwa ti gbe ilu Naijiria ga, ati wipe Apapa papa ti di ilu, o si ti di ile işẹ, bena si ni ọkọ Katilini ẹyọkan ko to mọ fun ẹniti o nlọ ti o nbọ.

Lakotan ara, Ebute Apapa nfẹ atunşe kiakia nitoripe ẹmi ọmọ enia ko pe meji.


## Consult us First about all your Problems

We are Specialised in buying and Selling of Houses & Landed Properties, General Merchandise Goods of all Kinds, Estate Managements, LANDLORD and Tenancy Services Rendered.

Apply to :-

B. OGUNLANA ONIKOYI
Licensed Auctioneer
etc, etc, etc.
Phone 23354

MART:-
55 Great Bridge Street
Lagos Nigeria.



DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

## MODUPE PRINTING PRESS

16, Bamgbose Street, Phone 21985
LAGOS


# ESI SI ORO OMO-ALARA OMO ORO

Moki Olotu pe gbogbo nkan ti ẹ ba fi ọwọ le, rere ni yio ma jẹ, ati pe oluwa yio fi fun nyin ju ibere yin lọ. Amin. Mo ki Ọgbẹni A. A. Ọmọ Alara, mo ri ọwọ rẹ, ati pe ọrọ rẹ fẹ faramọ imọ ọpọ enia, şugbọn imọ ọpọ enia ti o mọ na jọ imọ ọpọ enia ara Galantia.

Nitorina ẹ le ri apejuwe ọrọ na ninu iwe mimọ Bibeli iwe owe ori 10: 23-24 pe bi ẹrin ni fun aşiwere lati wu iwa ika, şugbọn ọlọgbọn ni ọni oye, Şugbọn mo fẹ ki Ọgbẹni A. A. Ọmọ-Alara mọ pe ọdun kẹta ti moinmọin ti nro aşọ, ihoho ni akara wa, ati wipe aiko sanra Agbigbo ki şe ẹgbẹ Atioro a si le ri apejuwe ọrọ yi ninu iwe mimọ Bibeli oniwasu ori 7 : 8-9 pe opin nkan o san ju ipilẹşẹ rẹ lọ ati onisuru ọkan ju ọlọkan igberaga lọ. Emi ko ba tun fesi le ọrọ Ọgbẹni Ọmọ Alara, şugbọn ọrọ kan lọ bayi pe ẹ maşe da aşiwere lohun, ki ẹ ma ba da bi rẹ şugbọn ẹ tun da aşiwere lohun ki o ma ba jẹ ọlọgbọn loju ara rẹ, ni ipari ọrọ mi yi, mo ro pe ewe ni a si nja yi, şugbọn ni igbati a ba wa egbo ọrọ yio buru ju bayi lọ.

Emi ni
E. O. Owuye, ọmọ Ajanaku bi ki yara. Ọmọ Erin bi Erin nijọ.

---

Olotu jọwọ gba mi laye lati fesi si ọrọ Ọgbẹni wa Alara ọmọ Oro sọ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti o jade ni 23/4/58

Esi mi si ọrọ Ọgbẹni wa na nipe, o dun mi pe ki nşẹ ọmọ Oro ni işẹ, ibajẹpe o jẹ ọmọ Oro ni, iru ọrọ na ko ni jade lẹnu rẹ, nitoripe gẹgẹbi o ti sọ yẹn, kişepe on pari ija rara, nşe ni on ndakun, ẹni to ba ni oye kisọ ọrọ bẹyẹn rara.

Bi enia yio ba pari ija, yio pari rẹ ni aiko fara kọ ẹlẹjọ kankan, bi o ba jẹpe o ro ọrọ na jinlẹ daradara ni, iba mọ bi on yio ti şe fun awọn toku, ti ibiti wọn kọ ile-iwe na si ko je ohun ti o dun mọ ni suru, Nitorina Ọlọrun si sọ ninu iwe mimọ pe "Alabukun fun ni awọn onilaja nitoripe ọmọ Ọlorun ni ao ma pe wọn" şugbọn ki şe pe bi wọn ti şe apari ija ni Ọgbẹni wa şe yẹn, bi o ba ma fun wọn ni suru, a fun wọn ni suru, şugbọn pe ni yio ma sọ pe ki wọn pada sọdọ ẹgbọn wọn, ko tilẹ jẹ on to dara to, ẹniti o ba jẹ ọmọ Oro kole lanu sọ iru nkan to sọ yẹn rara, nitoripe ko ni fẹ ki ede aiyede şẹlẹ larin ilu rẹ ati ilu miran ninu eku mẹşẹsan ati Esiẹ şe ọk wa iru eyiti wọn ba kọ tẹ ninu gbogbo wọn ati bi wọn ba şe tẹ wọn tẹle ara wọn ko so sinu Irohin Imọlẹ ti o fi wa jẹ pe o le ma pe ilu kan ni ẹgbọn fun ilu kan tabi ilu kan ni aburo fun ilu kan, ibiti inu nrun ti alayeluwa ọba wọn niki wọn fẹwọ wọnu ko sọ sinu iwe bakanna, o yẹ ki o gbọ itan ko to le ma şe alaye bẹ yẹn, koda o ko ro ọrọ na wo, o ko si fihan ẹniti o ni oye ki o to tẹ ade ninu iwe, o ko mọ ọna ti o fi ndaji gbe.

Ilu ti o ba jẹ baba ati ilu ti o ba jẹ ọmọ oninakuna, ki o şalaye sinu iwe bakanna, a ko ti ki ẹsẹ bọ odo, ọni nfa, ti a ba fi gbogbo ara bọ, gbigbe ni yio gbe ni mi. toto o şe bi owe o, Gẹgẹbi owe ti Ọgbeni wa na pa ni igbẹhin pe Bi a ba wa laiye, alaiye yio şaiye, bi a ko ba si mọ, alaiye yio ma şe aiye rẹ, şugbọn ajumọşe lodun, o tilẹ jẹ owe ti o fi dakun ede aiyede na.

Nitorina ni mo fi wa mọ pe, ibajẹ pe ọmọ Oro ni on işe ni, ko ba ti sọ bẹ rara, ko si wa mọ pe bi eke baro ẹjọ, ika kọ ni yio da, o sọ ọrọ ọlọgbọn loju ara re, şugbọn ọrọ omugọ patapata losọ, ko wa mọ pe arọ ti o daran, ọrun ẹlẹsẹ meji lo da si.

Mo rope Ọgbẹni na ko mọ pe ẹyin ni ọrọ, bi o ba ti delẹ fifọ lo nfọ, o ti da omi gbigbona pọ mọ titu, bi o ba ti şe yanju re, o ku sọwọ rẹ o. Ki o ma dakẹ ẹnu rẹ ti ede aiyede bẹ ba tun de.

Emi ni Awọlu matẹ

( Esi yoku di ọsẹ to mbọ )

**Akiyesi**

A nilo aṣoju ni awọn ilu wọnyi:- Iseyin Jos, Ondo, Ilesha, Ibadan, Ogbomọsho Saki, Kaduna, Ijẹdẹ, Oyọ, Ile Ifẹ, Zaria, Gbọgan, Kaba, Ota, Iluro, Aba, IKIRE kọwe si Olotu 16, Bainghose Street. Phone 21985.

# IRỌHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**GBANJO O!!**

Ẹnyin Alagbẹdẹ (Gold smith) ati Fadaka (Silver smith) E sare wa ra Ọpọku-Ọyọku "SILVER" E bere lọdọ :-

**Korede Store**
**108, Evans Street,**
**Lagos. Phone: 23336**

VOL. V No. 206 MONDAY MAY 15 — MAY 21 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Ejo awon Olorisa Elegba ti abule ilogbo bere ninu kotu ti Yaba ni oke Ebute meta.

YABA:- IROHIN KAN WA WIPE, AWỌN ỌLỌPA ROGIRI TIPA-TIPA WỌ IGBALE IBITI NWỌN GBE NṢE AWO ELEGBA NI ILU KAN TI O MBẸ NI ETI ỌSA NI EBUTEMETA TI A NPE NI ILOGBO NWỌN SI KO GBOGBO AWỌN ENIA TI NWỌN BA NINU IGBALẸ NA LỌ SI ITIMỌLE.

ASI TUN GBỌ WIPE, GBOGBO AWỌN ENIA TI ỌLỌPA RI KO NINU IGBALẸ NA JẸ ỌMỌ IMỌLE ORUKỌ WỌN NIYI:— RASAKI LAWAL, RASAKI KADIRI, MOSES ỌLỌJẸDE, YESUFU FALỌLA, BRAIMỌ ABUDU, RABIYU AWOTUNDE, LATIFU GIWA, SANUSI ANIMASAHUN, LASISI AKANBI FASASI LAWAL, OLUBI AKINSANYA MỌMỌDU LANGBE, BELLO JINADU, BELLO FARO, LADELE OSHODI, SULE YESUFU, JIMỌ BRAIMỌ, ABU LAWAL, RAIMI OLOKUN.

Pantiwa! bawo ni ọrọ na ti rin ki o to di ogun Kotu? Ọkunrin kan ti o njẹ Osuji lo njẹri niwaju Adajọ wipe nialẹ ẹjọ kan ninu oṣu April, bi on ti gba ọna Ilogbo lọ si Apapa, ni on ri ọkunrin kan ti o ngun Kẹkẹ Biasikolu lọ niwaju on, akoko na si jẹ agogo mẹwa abọ alẹ. Lojiji ni on ri awọn ogunlogọ enia ti nwọn rọ giri ti nwọnsi bọ ọkunrin na mọlẹ. Mọ wa ngọ ti ọkunrin na nkebosi bayi wipe, Ṣineke ! Ṣineke !! ni ede Ibo, itumọ rẹ ni wipe, Ọlọrun o ! Ọlọrun o !! pẹlu bi o ti nke toyi, ose ni nwọn fa a wọ inugbo lọ.

WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

# Awon enia pataki se iranlowo fun eko awon Odi

Ijọba Iwọ Orun kọ ile ẹkọ kan si Ibadan nibiti nwọn o gbe ma kọ awọn ti ko gbọran ati awọn Ayadi ni ẹkọ tobẹ ti nwọn o fi wulo fun ilu wọn.

Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe ti iṣe Gomina agba fun ilẹ Naijiria lọ bẹ ile ẹkọ awọn Odi wọnyi wo nigbati o de ilu Ibadan, o si fi ogun pọnun da wọn lọla, fun ilọsiwaju ile ẹkọ na.

Ọlọla Adesọji Aderẹmi, Alaiyeluwa Oni Ile Ifẹ ati Gomina ile Iwọ Orun fi pọnun mẹwa ati Ṣile mẹwa da ile ẹkọ awọn Odi na lọla.

Oloye I. B. Akinyẹle Ọba ilu Ibadan fi pọnun mẹdọgbọn da ile ẹkọ na lọla, diẹ ninu awọn ti o tun da ile ẹkọ Odi na lọla ni wọnyi:- Ogbẹni N. Abisakeni da pọnun mẹdọgbọn, Oloye A. O. Makanjuọla da pọnun mẹwa ati ṣile mẹwa. Ilewe Saint Anne's da pọnun marun ati ṣile mẹsan ati kọbọ meji.

Awọn ti o tun dawo ni A. J. A. Olufawo £2-2/- C. O. Phillips £2 2s od. D. A. R. Alexander pọnun meji (£2) ati Ọgbẹni J. A. Ọkẹ da Ṣile mẹwa 10/-.

**MOGBAYI BABY MIXTURE**
OLURANLOWỌ FUN AWỌN ABIYAMO




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni aṣepe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ odun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awon iṣẹ ribi ribi ti o ti nṣe.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to, dara fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu Ọmọde, jẹdi jẹdi, kokoro ori ọmọdẹ. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afọjuba egbogi yi. Atan yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko ṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra tirẹ ni ile itaja Egbogi town ni Adugbo rẹ.

Igo kekere re jẹ 2/6d    Igo nla jẹ 4/6d
**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*
**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria, Phone 22313
34, Docemo Street, Lagos, Phone 24247

**IJAFARA LEWU**

**Ma tan Ara re je mo!**

Bi o ba daju wipe IKỌ tabi amọdi " IGBAAIYA" lo nyọ ọ lẹnu ti ọjọ rẹ si ti pẹ pupọ, ma tan ara rẹ jẹ mọ nipa rira awọn "EGBOGI RỌBIRỌBI" ti nwọn nta kakiri ode nisinsinyi ni owo pọku. Wọn ko le ṣe iwosan "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ rara. Ṣọbu kan na ti o le ri orişirişi egbogi "IKỌ" ti o daju, atamatase, ati ajẹbidan lati Ilu awọn Jamani, Faranse, ati Lita (Tatanbuluj ra ni Igboro Ilu Eko tabi ni Naijiria ni ṣọbu awọn ara Ilu Saro ti nwọn npe ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos. Phone: 22875
NIGERIA. (Oja ita Fall)

# Ara Ajasse-ipo oto akoko lati jawo kuro ninu iwa Ikorira

Lati Ọwọ:- Isaac A. Olaitan

Bibeli Mimọ sọ wipe ko si ohun titun labẹ Ọrun nitorina ọrọ ti mo fe sọ yi papa kiṣe eyi ti a ko iti gbọ ri, ṣugbọn gbogbo akoko wa fun igba tirẹ, nitorina igba ọtẹ o ti koja lọ, nitorina gbogbo nkan ni o ni won fun wọn si, ki ẹ ma ṣe jẹki ti wa di aṣeju lọdọ Ọlọrun.

Iṣẹsin ọrọ mi ni pe, Ipo wo ni Ajassẹ wa loni ohun ti o mu mi sọ iru ọrọ yi ni pe ni ọsẹ ti o koja a gbọ wipe wọn ṣi ile ifiwe ranṣẹ kan nilu Idofian nitorina iru Ipo wo ni iwọ ọmọ Ajassẹ ipo ti o ra iwe Irohin na ka wa ati bawo ni ibanujẹ rẹ yio ti pọ to lori Ilu rẹ Ajassẹ-ipo.

Ni oṣu kejọ ọdun 1957 ni a ti bẹrẹ ile ifiwe ranṣẹ ni Ajassẹ, wọn si pari rẹ, ni oṣu keji ọdun 1960, owo ti ile ifiwe ranṣẹ na nawọn ni £1789:11s:2d. Sibẹ titi di akoko yi a ko iti si, Minista ti o wa fun iṣẹ na lọ sibẹ lati si. Iwa Ikorira ko jẹ ki wọn si, bẹni awa ọmọ Ajassẹ na ni afa ki wọn masi.

Nitorina ẹnyin ọmọ Ajassẹ ẹronu ki ọ si pa iwa yin da. Bi ipilẹ ba bajẹ kini Olododo yio ṣe, Ọlọrun koni jẹki ilu Ajassẹ ko bajẹ lori wa o.

Ki ẹ ma ṣe rope Ijọba yio ma fun wa ni nkan bi ẹnu wa ko ba ko, nitorina ki awọn kan ma bere, ki awọn kan ma sope koto ki ẹ ṣe fun tabi ki o ti ọdọ wọn ṣẹ. Bẹni ẹnyin alaṣẹ ti kuku ida wa lọwọ yin ko bere, nitorina o akoko fun wa lati di atunbi.

Ti ẹnu wọn ba dọgba, Ijọba ṣe tan lati ṣe ẹtọ wọn fun wọn, bi o ba jẹ wipe gbara ti apari ile ifiwe ranṣẹ (Post Office) ni a nlo ni ako ba mọ iru Ipa ti a o wa ni ọdọ awọn P&T papa, ao si ma ri iwe (letter) gba ni asiko.

Ẹnyin ti ẹ da ile ifiwe ranṣẹ (Post Office) ti akoko silẹ o dowọ yin o, bi Ipilẹ ba bajẹ kini Olododo yio ṣe bi ako ba si ile ifiwe ranṣẹ (Post Office) na, ni bo ni e o kọju si ninu ilu Ajassẹ, nitorina ki ẹ ma fi ti ẹlẹgbẹ de ṣe ilu Ajassẹ, nitorina Post Office yi ti gbogbo ọmọ Ajassẹ niṣe ati Alata ati Elepo, nitoripe lilo Post Office ni ogo yin ni Ajasse, ọrọ mi yi kiṣe pe mo nbẹbọ ṣugbọn lati tun ilu Ajassẹ ṣe ni, nitori iru iwa Ikorira bayi o ndoju ti enia larin Ilu miran.

## Egbogi fun Tita ati Iwosan orisirisi (Contd)

1. Anṣe orisirisi ojulowo Egbogi loke pẹ tẹsi yi fun tita ati fun Itọju orisirisi Aisan ati Amodi.
2. Anṣe Itọju Obinrin titi wọn yio fi loyun D. V.
3. Anṣe Itọju Aboyun titi wọn yio fi bimọ D. V.
4. Anṣe Itọju Obinrin ti nkan oṣu se mọ lara.
5. Anṣe Ajo fun t'Okunrin t'Obinrin ki wọn le riṣẹ ṣe.
6. Anṣe Ajo fun Obinrin ki o le ri ọkọ fẹ.
7. Anṣe Ajo fun Ọkunrin ki o le ri aya fẹ,
8. Anṣe Ajo fun Oniṣowo ki wọn le ma ri ọja ra, ati ki wọn le ta daradara.
9. Anṣe ajo ki Irẹpọ wa larin t'Ọkọ t'Aya.
10. Anṣe Ajo ki aranṣẹ le ba ni kale san gbese tabajẹ
11. Anṣe Ajo fun Iṣẹgun fun nkan jijọdu tabi ọta ati Ẹjọ Court.
12. Anṣe Ajo oju didun.
13. Anṣe Ajo fun Adakole pẹlu Imarale-aleko ọkunrin.
14. Anṣe Ajo fun Ẹyọnu Aiye, Ẹyọnu awọn Iya wa.
15. Anṣe Iok fun kikọ Petition
16. Anṣe Egbogi Isoye ariaim kanle bori tabi (Pass) orisirisi Idanwo (Examination).
17. Turari arisiki, lojojumọ fun Itaja, Itaja, o si tun nle Ajọnu buburu kuro nile.

Cigarette Cup, or Packet 10/-, 5/-, 2/6

J. B. CROWNSON ODUJOBI
Top floor: 16 Bamgbọṣe Street Lagos
PHONE 24318.

# KERE O! AKIYESI PATAKI

'Awa na le jẹ wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, Awa na nlo Ilu Gold Coast (Ankara) Ghana pẹlu, meji re kosi ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




## Irohin kakiri Igboro ilu EKo

Bẹna si ni ewẹ ni Igbro Ilu Eko, irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia' tọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi ṣe ọrọ ati orin kọ larin ara wọn jẹ nipa ti Egbogi Jamani olo kiki yi ti wọn npe ni Leopills.

Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti wọn ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamataṣe fun iwosan JẸDI-JẸDI bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti le pẹ to bẹna si ni awọn tun le fi owọ sọ aya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amọdi tabi aisan bi Akọ Inarun, Lakuregbe,, Ẹjẹ dudu lara, Arun Edọki, Iju Igbẹsise, tabi aikori Igbọnsẹ dede, Inurirun nigbakugba, Ara-wiwo, Esanri Ehin didun, Oju sisan tabi Aiko riran kedere, Kokoro buruku lara, Osi Inu Onigbameji, ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu. "Wipe" wọn yio ri alafia ni kiakia bi awọn ba nlo egbogi 'LEOPILLS' nitoripe a si ma tun ejẹ ṣe lara enia nipa si sọ di ọtun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ
IJAFARA SI LEWU PELU (POSTAGE 1/9d)

Egbogi Leopills:- Igo nla Ṣile mẹfa pere ni.
Igo kekere:- Ṣile mẹta abọ pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orisirisi amodi ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palm Church Street P. O. Box 333 Lagos Nigeria Phone 22878.** ati pẹlu ni Ṣọbu arabinrin Mrs C. O. Babajide near Health Office Ibadan ati ni Abinbọla Medicine Stores 829 Okesha Street, Ilesha Bisale Medicine Store British & Foreign Medicine (Dealer) S W 6/458 AGBOJO STREET, IBADAN, N.

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe ṣọbu ti wọn nta lo gbe ranse lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta adamọdi tabi oriṣi omiran fun ọ o maṣe gba rara.



## Nigerian Ports Authority

### INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the undermentioned scrap materials:-

| Lot No. | Location | Description | |
|---|---|---|---|
| 1 | Apapa Quays | 2 Steam Cranes Nos. PEL 11 & 12 | |
| 2 | " | 1 Ransome & Rapier Crane No. 2 | |
| 3 | " | 3 Coles Cranes Nos. 1, 3 & 4 | |
| 4 | " | 1 Land Rover, Registered No. G. 4405 | |
| 5 | " | 2 Cookers | |
| 6 | " | 6 Refrigerators | |
| 7 | " | 15 Easy Chairs; 9 Writing Tables; 4 Mirrors on Stands; 3 Bed Frames; 2 Pairs Bed Ends; 1 Chest of Drawers | as one lot |
| 8 | Apapa Quays | 53 Vehicle Batteries | |
| 9 | East Mole, Victoria Beach | Steam Locomotive No. 1159-1914 | |
| 10 | Apapa Dockyard | 1 60 Ton Lighter No. L. 50 | |
| 11 | " | 1 Pontoon | |
| 12 | " | 1 Crane Boiler No. 91509 | |
| 13 | " | 1 Crane Motor No. 55514 | |
| 14 | " | 1 Slipway Motor | |
| 15 | " | 19 Refrigerators | |
| 16 | " | 225 4-Gallon Kerosene Tins; 275 5-Gallon Drums; 60 Carbide Drums; 76 10-Gallon Drums; 100 44-Gallon Oil Drums; 110 44-Gallon Colas Drums | as one lot |
| 17 | Port Harcourt Quays | 2 Muirhill Shunters, No. 1 & 2 | |
| 18 | P. Harcourt Dockyard | Quantity Miscellaneous Scrap (Ferrous Metal) | |
| 19 | Calabar Dockyard | 4 Coal Tubs | |

2. The above items may be inspected on application to the following officers of the Authority between the hours of 8 a. m. and 12 noon not later than Saturday, 27th May, 1961:-

| | | |
|---|---|---|
| Lots 1 - 8 | - | Senior Stores Officer, Apapa Quays |
| Lot 9 | - | Works Supervisor, Victoria Beach (Tel. No. 20469) |
| Lots 10-16 | - | Senior Stores Officer, Apapa, Dockyard |
| Lot 17 | - | Senior Stores Officer, P. Harcourt Quays |
| Lot 18 | - | Senior Stores Officer, P. Hacourt Dockyard |
| Lot 19 | - | Harbour Master, Calabar. |

3. A copy of the Tender Form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 to the Authorithy's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays The completed Tender Form should thereafter be returned to the Secretary in sealed envelope marked "CONFIDENTIAL - Tender for Scraps" so as to reach him not later than Saturday, 3rd June, 1961.

4. The deposit of £5 will be refunded on receipt of a bona fide tender.

5. The successful tenderer in each case will be required to remove the material at his own expense within 21 days of acceptance of his offer.

6. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 574
12th May, 1961.

### O BERE LATI OJU EWE KINI

Ọkunrin kan ti o tun wa jeri ni Ọgbeni Paul Adebayọ Bello ti iṣe ọga agba ni ile ọgbọn nibiti a gbe ti le mọ ẹjẹ enia yatọ si ti ẹranko ti o nbe ni tosi Oshodi lo wa jẹri ninu kotu.

Nigbati on lọ si Igbale, ni ibiti awọn ti ngbe oriṣa Ẹlẹgba jade, on ri awọn nkan ti ẹjẹ tasi ara rẹ, on si diẹ lara awọn apa ẹjẹ na, ati nigbati on si ṣe ayẹwo awọn ẹjẹ na, on ri pe, ẹjẹ enia ni. Ni abawọ igbo Ẹlẹgba yi ni abule Ilogbo, on ri irun dudu ti o lẹ mọ ara nkan, on ṣe akiyesi wipe irun na jọ ti enia.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16 Bamgbose Street Lagos Phone: 21985. Olotu: E. A. Adenij 51, Tejuosho Street Surulere, YABA.

## Nigerian Ports Authority

### INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st July, 1961, to 31st December, 1961, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay, or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa area.

2 Tender indicating a price per ton should be submitted in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" and adressed to the undersigned so as to reach him not later than Saturday, 27th May, 1961. Late tenders will not be considered.

3. The successful tenderer will be required to remove at his own expense, whatever scrap is available for sale (with the exception mentioned above) during the six month period indicated within 7 days of the Authority's notification of such availability and will be required to make the necessary arrangements at his expense for all the scrap removed to be weighed in the presence of a representative of the Authority.

4. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender

*BAYO KEHINDE,*
*Secretary to the Authority.*

N. P. A. Notice No. 575.
12th May, 1961.

ADVERT. NO. 58.

### Correspondence on Pensions Matters

It is notified for general information that the former pensions Section of the Ministry of finance has now been itegrated with the Penions Branch of the Ministry of Establishments. In future all correspondence on any espect of pensions matters should be addressed to:-

The Permanent Secretary,
Ministry of Establishments,
(Pensions & Gratuities Branch)
Lagos.



## KERE O, Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹyin Abiyamọ lokunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ. E ku afojuba E g b o g i pataki ti aṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Oniṣegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakale Arun wọnyi:—
IGBONA:- Eyi yi je Arun ti o ṣopọ ni ode isisinyin papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.
ORIFIFO TULU, LUKULUKU, OTUTU IGBA AYA ARA RIRO, ati OTUTU ORẸREN pelu AKOKORO.
Jọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko to Afojuba.

Bere iwe ti o fi lo lọwọ eniti o ba ta E g b o g i na fun yin. Odeju hanwun, Ẹ o ri iṣe rẹ lẹhin iṣẹju mẹdogun ti e lo. Bere lọwọ awọn oniṣegun adugbo rẹ.

*Distributors*
HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23745
LAGOS